LIBRARY 28 FEB 1966

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,696 SATURDAY, FEBRUARY 12 1966 (2D)

## Adamodi Ṣọja kan W'ẹwọn Oṣu Mẹfa

LỌKỌJA. Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ni Adajọ kotu kekere ti ilu Lọkọja paṣẹ pe ki ọkunrin ọdaran kan Joseph Iyarhemer ti o pe ara rẹ ni ṣọja eyiti o si nfi ọna jibiti jale kakiri yara lọ fi ẹwọn oṣu mẹfa jura.

Ninu ọrọ ọlọpa to ba ọdaran adamọdi ṣọja na ṣe ẹjọ ni o ti ṣe alaye fun adajọ kotu na pe Joseph Iyarhemen nfi ọna eru gba owo lọwọ awọn enia ati pe o si nfi iya jẹ ọpọlọpọ awọn enia to ba nlọ ni oju ọna, eyiti o tun ṣe alaye fun awọn enia pe ọkan ninu awọn ṣọja ni on iṣe.

Ninu ọrọ ọdaran adamọdi ọlọpa na ni o ti ṣe alaye fun ile ẹjọ pe on jẹ oṣiṣẹ ni ile Iṣẹ ti nwọn ti ngba iwe aṣẹ lati lọ si ilẹ okere ni ilu Kano Ipinlẹ Ariwa.

Nigbati adajọ ile ẹjọ na bere lọwọ ọdaran adamọdi ṣọja na pe o jẹbi ẹsun na tabi ko jẹbi? Ọdaran na si dahun pe on jẹbi. Lẹhinna ni adajọ ile ẹjọ na ba paṣẹ pe ki ọdaran na yara lọ si ẹwọn oṣu mẹfa.

# IRINWO (400) ENIA TI PADADE SI IWỌ ORUN !

OGBOMỌSHỌ:— Idunnu ṣubu lu ayọ, ayọ si ṣubu lu oyin nigbati awọn enia ti nwọn ti sa fi ilu Ogbomọṣhọ sile lati inu odun to koja lọ yi bẹrẹsi maa de si inu ilu na pada ni ana ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi lẹhin igbati awọn enia na ti lọ to nkan bi oṣu meji ni ilu Dahomey.

Onirohin wa ni ilu Ogbomoṣho fi ye wa ni alẹ ana wipe, nigbati ilẹ ana ti bẹrẹsi ma mọ, ni mọto awọn Ọlọpa ti nwọn fi nko ero ti bẹrẹsi maa awọn enia na wo ilu wa.

Nigbati mọto na wo ilu, ariwo ta gee fun gbogbo awọn enia ti nwọn wa ninu ilu na nigbati nwọn tun fi oju kan awọn enia wọn pada ninu ilu na ni ana.

Onirohin wa sọ pe, moto akero awọn Ọlọpa mẹrin lo ko awọn enia na ti mọto na si kun ni akundẹnu.

Onirohin wa ṣe alaye ninu iwe ti o kọ si wa ni ana wipe, bi mọto na ti gunlẹ, ti awọn enia inu rẹ si fẹ maa sọkalẹ, ni on ba sare lọ si idi mọto na lati ya aworan awọn enia ti nwọn de ati mọto mẹrẹrin ti o ko awọn enia na de ati igbati nwọn nsọkalẹ ninu mọto pẹlu awọn enia sarakiṣaraki ti o wa ninu awọn enia na.

Ṣugbọn nigbati on de idi mọto na ni on ba ọkan ninu awọn Ọba alaiyeluwa Lawani Adeusi, Onijohun Ọba ilu Ijohun pade ninu mọto na bi o ti fẹ maa sọkalẹ ninu mọto na.

Bi Ọba na ti fẹ sọkalẹ ninu mọto na ni On we Irohin wa sare lọ pade rẹ ni oju ọna, ti o si ki ọba na tayọtayọ.

Ọba na sọ wipe, 'Inu mi dun lọpọlọpọ lati tun pada wa si ile. Iyọ ati ni alafia, ati pẹlu lati ba gbogbo awọn enia mi layọ, awọn ti mo ti fi silẹ lọ lati bi ọjọ mẹta.

'Ko si ibiti a le fi ile we, bi ajo ti wu ki o dun to ko le dabi ile ẹni ṣugbọn ninisiyi ti mo pada wa si ile ngo maa gbe papọ pẹlu awọn enia mi layọ ati ni alafia

Bakanna ni mo si tun mura lati maa sa gbogbo iranlọwọ ti mo ba si tun le ṣe lati maa ran Ijọba Ologun Orilẹ ede yi lọwọ ninu iṣẹ wọn ngo si jẹki gbogbo awọn enia ti mo jẹ Ọba le lori maa gbe pẹlu irẹpọ larin ara won gẹgẹbi ọmọ iya kanna

'Inu mi dun wipe, ohunti o mu gbogbo wa ti a fi sa kuro ni ile, ti kuro ninisiyi, ala fia ati Ijọba rere ti gbogbo awọn enia nfẹ si ti pada de si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nikẹhin.

EBUN ỌFẸ

Nigbati awọn enia de idi Jioko, Ọba ilu

WO OJU EWE KẸFA

## Okunrin Kan Ja'lẹ Nile Akintọla !

Gbogbo ile lo kunsoso ti ẹse ko si gbeji fun ogunlọgọ okeaimoye awọn e ia ti nwọn wa ninu ile ẹjọ kekere Ibadan ni ọpin ọsẹ ti o koja lọyi nigati awọn ọlọpa mu ọdaran kan, Titilayọ Asini ẹni dun meji— dinlogun wa si ile ẹjọ na lori ẹsun ole jija,

Ọlọpa ti o ba ọdaran na se ẹjọ se alaye fun ile ẹjọ wipe, ni ọjọ Abamẹta ti ise ojo karun osu yi, ni gbogbo awon enia bẹrẹsi sare lo sinu ile Ologbe Oloye Samuel Ladoke Akintola, Aare Onakakanfo, ẹniti o ti igbakan jẹ Alakoso Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun ri, ti awon na si nlo wo ile rẹ bi ni otito lo ti ku tabi irọ ni

Awọn enia miran tilẹ ti mo wipe o ti ku sugbon nwon tun osọ wipe awon sa fẹ lo wo inu ile re ki awon si ri bi o ti se ku ati ibiti o ku si

Nigbati awọn enia wọnyi bẹrẹsi ma a lo si ile Oloye na lati ma lọ wo ibiti o ku si, gbogbo adugbo na wa dabi igbati awọn enia ba nlọ ọja ti awọn enia na si pọ lọ bi ewe rumọ.

Ṣugbọn nibiti awọn enia ti nworan lati wo ibiti Oloye Akintọla ku si na, ni ọdaran kan, na ti ọwọ bọ inu apo ẹwu ẹnikeji rẹ ti o si mu pọnun kan sile mẹsan ati tọrọ (£1 : 9 : 3d) nigbati awọn enia nti ara wọn lati wọ inu ile lọ, ṣugbọn nigbati ọdaran na lẹ salọ mọ awọn enia na lọwọ ni nwọn ba ragabu rẹ ti nwọn si mu lọ si Tesan awọn Ọlọpa,

Nigbati ọdaran na rojọ, ti o si gba wipe, on jẹbi ni Adajọ ba paṣẹ, wipe ki o lọ si ẹwọn oṣu mejidinlogun lai sfabala.



# ILU AWỌN EMERE (Apa 2)

**Lati Owo J. O. Shoyinka**

Ibiti mo ba itan mi de ni ọsẹ to kọja ni pe, iya arugbo kan sure fun awọn ikọ na ki awọn to bẹrẹ irin ajo wọn si ilu awọn Emere.

Alado Idẹ Papa Fesi

Bi iya arugbo na ti sure fun wọn tan, ti ọba papa se tun sure fun wọn bakanna ni Alado idẹ papa ba doju-kọ ilu, osi wi bayi pe nko le ṣai dupẹ lọwọ ọba ati ilu papajulọ, iya agba to ṣadura fun wa moti ba Ọlọrun da majẹmu kikun pe ao lọ re, ao si bọ re pẹlu ṣugbọn kinikan ni mo fẹ bere lọwọ ẹnyin ilu ṣe e bawa toju ile ati ọna wa ki a to de? Nito ripe mo ni ọmọ mẹfa alaini baba ni gbogbo wọn. Iya mi si ti d'arugbo kẹgẹkẹgẹ ṣugbon ifẹ ilu ti mo ni lọkan ni o ngbe mi lọ yi ẹ dakun e ṣe adura fun wa ni arapo lẹẹkan si pe ao lọ re ao si bọ re, gbogbo ilu si panupọ pe awọn yio lọ re awọn yio si bọ re awọn ikọ na si ṣami

Bi ilu ti fẹ tuka ti awọn kọna si fẹ mu irin ajo wọn pọn ni okunrin alagidi kan ni ilu na ti awon npe ni Gbengbekuele ni ẹ duro na kẹkẹ si pa mọ gbogbo wọn lẹnu nwọn si tẹti silẹ la ti gbọ ọrọ enu rẹ

Gbengbekuele sọrọ

Gbengbekuele ki ara rẹ lo iti o ni enia ki lọ si ogun ki o ma diara ogun bi a ti ni oni yio ri ọla ki ri bẹ, toto o ṣebi owe o.

Ẹnyin ara ilu mi mo fẹ ki ẹ mọ daju pe awọn ikọ yi fi ẹmi wọn ji iku ojiji, ni tori ilu wọn, lotito nko de ilu awọn Emere ri, ṣugbọn laiṣe anisni mo fi oju inu wo pe ilu kan ti yio ṣoro tẹ ori wọ fun alaye ni! gẹgẹbi ẹ ti mọ, ni ti emi o Nko ni ọre meji ju awọn itunmalẹ ajẹ Oṣo ati awọn oriṣa inu emi lọ, nkii jẹun ni ile aiye agbedemeji ọrun ati aiye ni emi ti ma jẹun pẹlu awọn ajẹ ti mo ba si ya igbe nile aiye tan Aaja ni ma gbe lọ si ọrun. Ki si iru ẹda alaye ti nko le s ara mi da tẹ u.

Ni kukuru ki oma gba yin lesiko tori pe ọjọ n lọ

Ẹnyin ti mo ni ba sọrọ gan ni ẹnyin ti ẹ nlọ ilu awọn Emere njẹ ẹ ti di ara yin ni oriṣa bi?

Nwọn da lohun pe dọba Gbengbekuele fi ibere wonyi siwaju wọn Ggbengbekuele :- Njẹ ni irin ajo yin lọ si ilu Emere ti ẹ nlọ yi, ti ẹ ba ba awọn iwin pade lọna, ki ni ẹ o ṣe ?

Aledo idẹ dahun



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

Alado idẹ-Lotito ob arin atehinto ni emi iṣe ẹniti si ni iyalode ajẹ, ti a ba pa de awọn win, a go pitu me je. ti ọdẹ npa ninu igbo, ni titọ ni awọn win ko ni ẹjẹ pupa ni ara ṣugbọn wọn ni ẹjẹ funfun.

Bi o ba jẹ pe, nitoto ni mo jẹ ogun aje yi lọwọ iya mi ni, ngo fa ẹjẹ wọn mu pati pata, nwọn yio si kusi bamubamu ni

Okogaunbasi:Ni ti emi o koday ni emi iṣe, ẹbọra bamubamu ni emi si iṣe tẹ lẹ ri ati ajule ọrun ni mo si ti wa si ile aiye. Ẹbọra ko si ju ẹbọra lọ si mo ba pade awọn win lọna, bi oti wu ki wọn pọ to, nwọn yio gba mi ni ọga pe, ẹbọra ni emi papa iṣe tẹlẹtẹlẹ Nko ni sọ jubẹ lọ lẹ Ẹsun o'

Abonidepenu: Ni kuku ru ki to gba yin ni ase ko pupọ 'Moonu' ni oruko mi njẹ odi igo a ba bẹrẹ irin ajo wa na ki ẹ to mo pe okunrin ni emi ise ọrọ awọn iwin tabi awọn irun-malẹ ko jọ mi loju ti awọn ba pade wa awọn mọ gba Ọlọrun ni ọga toripe ibiti wọn bati pade wa ni ilẹ yio mọ wa si si.

Ẹṣu Orita:— Ẹ ku apejọ, ẹ si ku apero, Ẹ da mi da awọn ẹbọra, ewele, irun—malẹ ati alaj oma yio wu ki a ie ba pade ni irin ajo

Wo Oju Ewe Karun

# Ọlọlajulọ Ọbabinrin Ilu Oyinbo Ati Ọkọ Rẹ



Ọlọlajulọ Elizabeth Keji ati oko re

LONDONU:— Ni ibere ọdun yi ni Ọlọlajulọ Elizabeth Keji Ọbabinrin ilu Oyinbo ati ọkọ re, Oloye Ọmọ'ba Phillips ya awo-ran alarabara kan ninu aafin Ọbabinrin na ni Londonu gere ni ibẹrẹ ọdun tuntun yi.

Oniwe Irohin wa ni ilu ọba Ọba Oyinbo fi ye wa wipe, yeti goolu, ilẹkẹ go-oolu, ni Obabinrin na fi si ọrun re ni ọjọ ti nwọn ya aworan yi,

O tun ṣe alaye siwaju nipa ọrọ tẹ pẹlu wipe, ewu Ologun ni Ọlọla Phillips ti iṣe Duke wọ ni ojo na ti on ati Ọba'bin-rin na si ya aworan ninu ile wọn

Ṣugbọn siwaju eleyi ni Irohin kan ninu agbala Ọba'binrin na ti ṣe alaye wipe, ki awọn Oniwe Iro-hin na ti lo aworan na ti o aworan na tita di ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrindinlo gun oṣu ti o kọja lọ yi,

Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

# Ilu Awẹ Nfẹ Ina Mọna—mona

Olotu, Inu mi ylo dun bi ẹ ba gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati ki Gomina ologun Ipinle Iwọ Orun Naijiria Ọgagun Adekunle Fajuyi pe o ku iṣẹ ti nwọn nṣe fun wa ni Ipinle Iwọ Orun Naijiria Oluwa ko ni jẹki nwọn ṣi iṣẹ na ṣe amin.

Bakanna ni a tun dupẹ fun eto ti Gomina Ologun Ipinlẹ na ṣe nipa tt owo oṣu awọn Ọba ati Ijoye Ipinlẹ Iwọ Orun eyiti wọn ti fi igbakan da duro tabi pe ki nwọn ge owo oṣu wọn ku si kọbọ kanṣoṣo ni ọdun kan eyitl Go mina Ologun na pa laṣẹ pe ki nwọn tete yara san owo oṣu na fun awọn Ọba ati Ijoye ti awọn nkan bayi ṣẹlẹ.

Inu awa ọmọ Ilu Awẹ yio dun bi Ijọba Ologun ba le tete mu oju to ina mọnamọna ti Ijọba amọtara ẹni nikan Ijọba eru ti daduro ti nwon ko ṣe nkan—kan nipa ina na lati igba yi wa ati pe a fẹ ki Ijọba Ologun ba wa tete ṣe ẹto nipa ina mọnamọni kiakia eyiti aori lo ni Ilu Awẹ

Ilu Awẹ jẹ ilu ti o kun fun wara ati oyin ati pe ilu Olaju si ni o jẹ ati pe awọn enia to wa ni ilu na to 500,00, ṣugbọn a ko fi owo ori wa jafara a si lero pe Ijọ ba Ologun yio tete ṣe eto nipa ina mọnamọna na fun wa ati pe ilu Awẹ jẹ ilu to sunmọ Ọyọ pupọ.

Ijọba aua mu ina de ile ẹkọ Awẹ High School ati ile ẹkọ na ko ju ọgọrun ọpa si ilu Awẹ ṣugbọn awon to jẹ Ajẹni ṣeni ko jẹ ki ina na de ilu wa. Ninu awọn nkan ti a nfẹ ni ile Ifi iwe ranṣẹ nla eyitl a lero pe Ijoba Ologun ylo ṣe awọn nkan na fun wa laipẹ.

Emi ni
J. Olu Akintunde

EKO.

## Idahun si ọrọ Kogberegbe

Olotu, Jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ogbọn ati oye lati fun Woli Kogberegbe ni esi ọrọ rẹ kan to jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ karun oṣu yi eyiti o ṣe alaye pe Jesu jẹ ọmọ Ọlọrun ati pe mo fẹ lati fi we Kogberegbe to pe ara rẹ ni Woli pe ko ni ẹtọ lati ma sọ ọrọ ti ko ba oju mu si awọn ẹlẹsin miran.

Ọrọ ti Woli Kogberegbe sọ ni ọjọ karun oṣu yi pe were ni awọn enia to sọ pe Jesu ki iṣe ọmọ Ọlọrun, lẹhinna ko tun duro lori ọrọ rẹ o tun sọpe nigbati awọn Imale ba ti jẹ saari tan ti nwọn si fi ogurọ ati ẹmu sọnu tan pe nwọn a ma sọ pe Jesu ki iṣe ọmọ Ọlọrun.

Mo fẹ ki Woli Kogberegbe lọ mọ daju pe Ibiti imọ tirẹ mọ ni nyẹn lati fi sọ iru ọ r ọ be. Mo fẹ ki Woli Kogberegbe lọ mọ daju pe Ọlọrun fun ara rẹ sọ pe on ni ọba awọn ọba ati pe ẹnikan ko bi on, on na ko si bi ẹnikan. Nitori eyi mo fẹ ki Woli Kogberegbe lọ mọ daju pe gbogbo ọrọ ti o sọ pe awawi ni gbogbo rẹ si jẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ.

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o.

Emi ni
A. Ọlawale Odu-ọla

EKO

# KERE O

Nje o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA toṣẹ ṣẹjade ?

Ha ! Kosemani ni Iwe na jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan Iṣẹdalẹ Yoruba. Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Maṣe jẹki nwọn rohin itan Ilu rẹ fun ọ 3/- pere ni. Postage 9d

Tete fowo tirẹ ranṣẹ si:-

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria

# Ha Kini Eley




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLỌRI ERIN MẸTA

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara jul gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idu ,

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si danwo; iwọ yio ri bi o tiṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu ori erin mẹta ni nwọn mu fun ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ile itaja kakiri Orilẹ ede yi

Distributor
AMOS GBENLE & BROTHERS
34: Docemọ Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West

BERE FUN OJULOWO EGBOGI—

# "Congreve's Iodo Form—Oinment



Atamataṣe ni egbogi" ADI-BLEGBO" yi jẹ fun itọju gbo gbo orișirișl "EGBO—ẸSẸ" ni kiakia bi o ti wu ki ọjọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni egbo nipa wipe awa ko idọti ni bi ẹri gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re ylo si mo daradara .Lẹhinna oju egbo yi o ba jẹ sinu yio jẹki oju re hu wa soke, yio si pọn daradara tun bakanna ko si mọ aerewere ni ylo si san patapata Alafia de si ọ niyen :—

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won absalc iwe yi ni ogbe ranṣẹ lọ ra. Bibeko awon Elero hii on ijibiti ylo ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba rara ọ

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Ola Ita Faaji)
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos

# Ikomo Ajose Larinrin

MUSHIN:- Idunnu subu layo ni ojo ojo'Ruti ise ojo keran oju yi nigbati omo Oba Rauph Akanbi Ajose nse ayeye Ikomo jade omo binrin titun jojolo ti Olorun fi ta on pelu iyawo re Rafatu Olasunbo Abebi lese ni nomba 4A Oguntoye Street, Mushin to je wipe gbogbo ile awon Obi omo titun na lo kunsoso ti ese ko si gbeji fun oguolo-go okeaimoye awon ore, ebi, ati ojulumo to wa sibi ayeye eye ikomo titun na jade ni ojo na.

Enu si ko irohin ni ale ojo ti omo Oba Rauph Akanbi Ajose nse ayeye ikomo titun na jade eyiti o je wipe gbogbo adugbo Oguntoye Street lo kun fun awon alabaseye lokunrin ati lobinrin to wa sibi ayeye ikomo na jade ni ojo na.

Nigbati ile ojo na ti mo ni awon Alufa, Alhaji ati awon Lemomu pataki ti nwon mo nipa eto ona esin islam ti nde si ile baba omo titun na lati se eye isomo loruko eyiti nwon si se eye re ti nwon si so omo binrin jojolo na ni Romo-salai Fadeke Ayoku Ajose.

Baba omo titun na si na wabi-wosi owo fun awon Afa ati awon Alhaji to wa se eto isomo na loru-ko bi baba omo titun na ti ngna-wo beeniiya omo titun na tun ngnawo pelu bakanna ni awon ore ati ebi baba ati iya omo na si tun na wabiwosi owo ni ojo na.

Nigbati o ti di deede agogo me-jila osan ojo na ni awon ore baba omo ti nwon jijo nsise ni ile ise si Ijoba ibile Mushin (Mushin District Council) beresi ni de sile baba omo na.

Lehin eyi ni Fatayi Ayilara ati awon Elere re tun wa beresi fi ilu apala re da awon alaba-seye ojo na laraya, Baba omo na si na wabiwosi owo fun awon Elere na. Gbogbo awon ore ba-ba omo ni o nawo nara ni ojo na paapa julo Ogbeni Oladipo Adisa ti ise ore korikosun baba omo na si se beje nibi ico no na

Eleyi ni die ninu awon eniyan pa-taki ti a ye wa lati daruko won ninu awon enia to wa sibi ayeye ojo na ni Ogbeni S. A. Okunakin de Akowe agba egbe odo Afenife-re ti Mushin ati agbegbe re, ogbe-ni Alimi Sunmola ti o je okan ni-nu awon Makaniki ni ilu Mushin, Ogbeni Dairo Afunku ti o je Ako-we eto ise ninu ile ise Ijoba ibile Mushin. Oladipo Adisa, Oga agba ni eto akoso ise ninu ile ise Ijoba ibile Mushin Ogbeni S. A. Ose-gbenro Oga agba awon Olopa ti Ijoba ibile ni ekun Ikorodu.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 21 Fep 18) Iwo yio rinna pade orire kan loni ni ona lyanu ti o ko lero re tele.

PISCES (Feb 19 March 20) Osepa ti o wa loke orun yi yio jeki o ri iranlowo lati odo awon enia kan gba loni eyiti yio se o ni anfani ni ojo iwaju

ARIES (March 21 April 20) Ogbon inu re ni k o maa lo loni ma si se ba enia kan ko egbe papo ki nwon ma pa se ye imoran re jato si ohunti o fe se

TAURUS (April 21 May 21) Mase ba enikankan ja loni, ki o si lo ni opolopo suru si awon ohun ti o ba nse, ki owo re le ba te ire ti o wa ni oja re loni,

GEMINI (May 22 June 21) Ogbon inu re ati iwa pele yio jeki o se orire loni ninu ohun kohun ti o ba da wole lati se

CANCER (June 22 July 22) Gbogbo awon ohunti o ba da owo le loni ni yio yori si rere, sugbon sora pelu oro ti yio maa jade lenu loni, nitori awon abinu eni

LEO (July 23 Aug 23) Gbogbo ohunti o ba se loni ni yio maa yori si rere, sugbon sora gidigidi ki o ma ba se si oro so ni irole yi, ki awon enia duruku kan ma ba se ri tiran so

VIRGO (Aug 24 Sept 23) Awon enia ola kan yio se iranlowo fun o loni ti yio ri fi okan re bale ninu gbo-goo ohunti o ba nse, nitorina, maa yaju si enikeni

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Inu rere re yi gbe o ko oloriirekan lo ti yio mo iyi ise ti o nse ni ona ti yio fi yin o ni ona ti yio mu iwuri wa fun o

SCORPIO Oct 24 Nov 22) Iwo yio ri ebun nla kan gba lowo enikan ti o mo iyi ati imore ise re loni bo gbo enia lo ngbadun ise owo re, ma se yi iwa re pada,

SAGITTAAUS (Nov 23 Dec 21) Iwo yio ri Irohin ayo kan gba loni ti yio mu inu redun,beeni gbogbo nkan ni yio si dara fun ni ale loni

CARICORN Dec 22 Jan 21) Gbogbo awo ohunti o ba fe se loni, lo ogbon inu re lati se won nitoripe ogbon inu ni ejo nlo


GBOGBO ARA ILU NKO ORIN IYIN ATI OGO NIPA **DYNAMIREN** TONIKI



ALE-IBI-ALE Egbogi To ki amonu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mo oju fun Agba-ra ati Aiebidan se lara agbalagba Okunrin ati Obinrin gbogbo

Bi are ara ba nmu o, ni gbakugbe fun wahala tabi ise sise ti o ko le jeun dara dara, tabi ki o male sun da da de okan losan tabi awon san ara re gbogbo ki se fun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunle daradara won ise tabi wahala sise tabi inu awon ailera gbogbo ayin ti ojo ori (ago) ba ti koja ogbon odun si adorin tabi jube lo mo daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfe lati so ara re di otun pata oju re yio si wale re kete alafia ati igbadun de Bere Dynamiren yi ni Sobu awon :-

Waterloo Medecine Stores
8, Palm Church Street P. O Box 333 Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street,Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.
ADEDUN CHEMIT
14, Wakeman Street
ATI NI SOBU
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA
IBADAN

a successful future

means planning *Now!*

Have you planned for the security of your family's future? Start a programme of Life Insurance NOW

*with*

**GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,**
(INCORPORATED IN NIGERIA)

Enquire now for full details of our low cost endowment policy.

HEAD OFFICE:

39/41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2314, LAGOS
TELEPHONE 25251.

BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA.

# IWA OMUGỌ NI YIO PA AWỌN ELẸ'GUN

## Lati Ọwọ Woli Kogberegbe

Mo ki gbogbo ẹnyin olugbọ ọrọ mi ati Olotu wa pẹlu alafia Oluwa yio ma ba nyin gbe o. Mo fẹ ki gbogbo enia lọ mọ pe iwa omugọ ni yio pa Elegun, ni ọjọ kan mo lọ si ilu Lalatẹ lọdọ ọrẹ mi kan, nwọn ṣe mi alejo rẹpẹt, awọn enia si nsọ pe ṣe emi ko ni lo woran Ọkdiran ?



Woli Kogberegbe

Ọrẹ mi yi si sọ fun mi pe egun ti nṣidan ni ilu awọn yi lo njẹ bẹ. gbogbo awọn enia to w ni ilu ni ma nwa sibẹ lọdun tọ ba fẹ pidan na, mo bere l'ọ w ọ ọrẹ yi pe iru idan wo ni egun na yio pa to dun to yi ? Ọrẹ mi yi sọ fun mi pe inu ina egun yi yio ti o ba pẹ ti ina ba jo tan enia kan ko ni mọ asiko ti egun na yio kuro ninu ina na.

Mo si gba ọrọ ti ọrẹ mi sọ ti mo duro lati w o ra n awọn egun Nigbati ọjọ pe ni mo b ẹ r ẹ si ri orişirişi awon enia ti wọn b ẹ r ẹ s i ru koriko lọ si ọja ati ọpọ lọpọ ewe to ti gbẹ.

Awọn enia dabi oni eyiti o jẹ pe bi a ti duro ni awọn enia miran ru aṣọ egun de egun na si wa lẹhin nigbati o pẹ diẹ egun yi de pẹlu ariwo ilu bata pẹtu ljo

Gbogbo awọn enia naa sọ tun sa sosi, awọn nşubu lu ara wọn nigba to yẹ ni egun yi bẹ ko sinu koriko ti awon egun y ku si nran lo wo lati ko ewe gbigbẹ yoku le lori

Nigbati o pe egun na de hun labẹ koriko pe ki wọn fi ina si awọn yoku re si fi ina, ina yi si beresi jo gbo gbo enia si beresi wo won ariwo ilu si beresi ta

Gbogbo awọn to ti dagba sinu iwa we e ati ọmuti ti nwọn ma npe ni alaṣẹ to jẹ olori awọn alaşeiu gbo gbo w on lo wa n'ibẹ ti nwọn bẹresi jo ti inu won ndun ni teripe nwọn ni were ile ba ba won loni ina yi si njo ki kan Egun yi si bẹrẹsi pe ọfọ n'nu ina ọfọ yi ko da lohun egbe to jẹ ko gbe jade ina yi si ku diẹ ki o jo de ọdọ re egun yi tun pe ọfọ rẹ şu gbọn ọfọ re ko da lohun ina yi si bẹresi jo gidigidi eyiti awon enia si nsa sẹh'n

Bi agbara ina na ti pọ to koşe fẹnuso nigbati ọwọ ina fẹ te Egun yi ni o ba fa riwo ta pe Ọjẹdelo Ọjẹdiran ẹ jowọ ẹ şigo lori mi egun fẹ jona iyeru omo eru okan şugbon ariwo ilu ko jeki awon enia gbo igbe ti Egun nke ninu ina.

Nigbati ina de odọ re egun fi ariwo tu pe ẹ jowo ẹ şigo lori mi Egun fe jona iyeru omo eru okan a ni ẹ jowo ẹ şigo lori mi ani egun fẹ jona, egun fẹ jona.

Bayi ni owo ina şe to egun tiko ri ona jade egun si ku sinu ina nigbati ina yi jo rẹlẹ ti awon alaşẹ pe egun egun ko le dahun o to asiko to yẹ ki egun yi de ko de rara.

Nigbati nwon fẹ ma mura lati ma lọ ẹni okan ninu won fi egbogi si enu lati fi pe to si pe bayi pe Egun ile Ọjẹbo dẹ iyeru omo eru okan da mi lohun egun ti ku sinu ina ẹnikan ninu won ba lo wo inu ina na to ba egun na ti ina ti jo pa.

Nigbati iya ọmọ kunrin to gbe Egun yi gbọ iṣẹlẹ to şẹlẹ ni o ba fa ariwo ta Nitori eyi mo fẹ ki ẹ lọ mọpe ọpọlọpọ ni okun ti awon keferi nse to si nfa iku fun wọn ina Ọlọrun ko dun si enilẹ rara ha! gbogbo ẹnyin Elegun to wa lode aiye e sora nyin ki ẹnyin ma ba ri ibinu Oluwa.

Mo sinisisiy pe Oluwa tobi ju gbogbo orisa lo Eksode 18 ẹsẹ 11 Nwọn si rubọ si iwin buburu ti kişe Ọlọrun ati si orisa ti nwọn ko mọ ri si orisa ti awọn baba nyin ko bẹru. Apata ti o da ọ ni iwọ ko ranti Iwọ si ti gbagbe Ọlọrun to da ọ Deuteronomi 32 ẹ;ẹ17 nitori ẹnikẹni ti ko sa orisa silẹ were ni yio pa ni Oluwa wi. O di gba diẹ na.

## Lati Oju Ewe Keji

wa si ilu awọn emere. Bi ogo ba nje ti Ẹlẹda, n g o ş' eşu pẹlu wọn, ti nwọn ko ni gbagbe lailai.

Akiyesi: Ni ọsẹ ti m b ọ ti işe 19/2/66 ẹo ma ka bi nwọn ti şe pinya ati ọna ti Olukuluku gba itan y i n gun gan'an gẹgẹbi moti sọ fun nyin ọkan gbako ninu o fi ẹo fi kan legbara Ọlọrun, Ki nsi .o ba itan mi na de ori kẹrin, ẹo ma ka bi awọn iko na şe nlo orişirişi Ogun eyiti ẹnyin paa pa yio ri mulo ninu rẹ. Alafia Oluwa ki o ma ba ẹnyin ati Olotu g b e pẹlu awọn alaba şişẹ pọ rẹ.

Odigba kanna O.

# Iwe Itaja 1966

Idamu owo ha wa fun ọ bi
Abiku ha nyọ ọ lẹnu bi
Airi iṣẹ se ha wa fun ọ bi
Ailera mba ọ ja bi
?

Iwọ le bọ ninu gbogbo wahala aiye wọnyi ti iwọ ba ra ninu awọn ohun Ijinlẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ti a to lẹsẹsẹ si isalẹ yi.

1 Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6
2 Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 4/6 di 3/6
3 Iwe Itumọ Ala ati Ogun Wibẹjẹbẹ 4/6 di 3/6
4 Iwe Egbogi Awoɀba Arun 20/— di 17/6
5 Iwe Ilana Ifa Yanrin tite ati etutu sise 20/- di 17/6
6 Gbedegbẹyọ Hausa 3/—
7 Iwe Aniyan Irun 2/— di 1/—
8 Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Itaja 10/6 Pangolo 2/6 paket

Fi Owo ranşe si

J. O. SAOYINKA
P. O. Box 159
MUSHIN

tabi

9, Iyala Street Oduabọrẹ, Mushin

